# IWE TI A KỌ SI ARA OGIRI

### Daniẹli 5

### ẸKỌ 422 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Oluwa mọ̀ bi ã ti iyọ awọn ẹni iwa-bi-Ọlọrun kuro ninu idanwo, ati bi ã ti ipa awọn alaiṣõtọ ti a njẹ niya mọ dè ọjọ idajọ" (2 Peteru 2:9).**

**Ase Bẹlṣassari**

Bẹlṣassari ni ọba Babiloni ti o jẹ kẹyin ni akoko ti ijọba Babiloni jẹ́ alakoso gbogbo ayé ni igba laelae. Nebukadnessari, baba rẹ̀ agba, ti sọ ni opin ọ̀rọ rẹ̀ pe Ọlọrun Israẹli ni Ọba Ọrun, ati pe iṣẹ Rẹ̀ "iṣe otitọ, ati gbogbo ọ̀na rẹ̀ iṣe idajọ: ati awọn ti nrin ninu igberaga, on le rẹ̀ wọn silẹ" (Daniẹli 4:37). Ṣugbọn ọ̀rọ ti o ti ẹnu ọba yii jade kò ṣe Bẹlṣassari ni oore. O gbé ara rẹ̀ ga o si ṣe ohunkohun ti ọkàn ibi rẹ̀ n fẹ́, lodi si ifẹ Ọlọrun.

Ni alẹ ọjọ kan Bẹlṣassari se ase nla kan. O pe awọn eniyan ti o lé ni ẹgbẹrun ninu awọn ọmọ alade Babiloni. Gbogbo awọn ọlọla ọkunrin ati awon obinrin ọlọla wà ninu aṣọ olowo iyebiye wọn; ni aisi aniani ohun ti o dara ju lọ ni ilẹ naa ni ji jijẹ, ni ọti-waini ati ni are-idaraya ni a fi fun wọn. Ṣugbọn kò fun wọn ni itẹlọrun. Eniyan kò le ni itẹlọrun laelae ninu awọn ohun ti ó wà ninu ayé ati awọn igbadun ti o lù mọ́ ẹ̀ṣẹ. Iwe Ọlọrun nikanṣoṣo ni ọ̀na si inu didun tootọ, Ó wi pe a o ni inudidun nigba ti a ba fi fun awọn ẹlomiran ti a si sẹ́ ara wa nipa gbigbe agbelebu wa tẹle Jesu lẹyin. Ọlọrun ni o dá eniyan, O si mọ ohun ti o le mu inú eniyan dùn.

**Fifi Awọn Ohun Mimọ́ Ṣe Ẹlẹya**

Bi awọn eniyan yii ti mu ọti pọ to, bẹẹ gẹgẹ ni wọn fẹ́ iwa ẹ̀ṣẹ tó. Nigba ti wọn kò mọ iwa buburu ti wọn tun le hù mọ́, Bẹlṣassari pinnu lati pe Ọlọrun ni ija. Ọpọlọpọ eniyan lọjọ oni ni wọn n lo orukọ Ọlọrun ati ti Jesu lati fi bura. Wọn n fi awọn ohun mimọ́ inu Bibeli ṣe ẹ̀fẹ, wọn si n fi awọn wọnni ti o fẹ́ wà fun Jesu ti wọn si n fẹ ṣe ohun ti o wu U ṣe ẹlẹya. Ọlọrun a maa mú suuru pupọ fun ẹlẹṣẹ, ṣugbọn o pẹ́ ni tabi o yá ni idajọ yoo wá si ori ẹlẹṣẹ naa bi o bá kuna lati ronupiwada. Lẹsẹkẹsẹ ni idajọ yara dé sori Bẹlṣassari ati awọn ọrẹ rẹ̀ buburu. Laaarin ase imutipara yii ni awọn ìka ọwọ eniyan kan jade wá lara ẹfun ogiri, o si kọ iparun ti yoo de ba Babiloni. Ohun abami bayii to ohun ti o le dẹruba ẹni ti ara rẹ̀ balẹ, eyi si daamu awọn wọnni ti wọn ti mu ọti yó, awọn wọnni, lai si aniani, ti ọkàn wọn n dá wọn lẹjọ nitori wọn gan Ọlọrun.

**Orunkun Bẹlṣassari nlu ara wọn**

Lẹsẹkẹsẹ ni ohun ti Bẹlṣassari ri mu ki ori rẹ wá si ile. Ẹ̀ru ba a to bẹẹ ti o fi fẹrẹ má le dide duro. Oun ko le ka iwe ti a kọ, bẹẹ ni kò si le sọ itumọ rẹ̀, ṣugbọn o ni idanilọju pe ihin buburu ni. Lai si aniani awọn ẹ̀ṣẹ ti o ti dá ni gbogbo igbesi-ayé rẹ̀ ni o wá siwaju rẹ̀, o si mọ pe oun kò lẹtọ si ohun rere kan. O n fẹ iranwọ, nitori naa o ranṣẹ pe ki awọn amoye rẹ̀ ati awọn alafọṣẹ rẹ̀ yara wá lati ka ohun ti a kọ. O wa di ẹni ti o lawọ o si ṣeleri ipo ọla nla fun ẹni ti o ba le sọ itumọ iwe ti a kọ fun un. Awọn amoye wá, ṣugbọn òye wọn nipa iwe ti a kọ kò tayọ eyi ti ọba tikara rẹ̀ ni. Nisisiyii ọba wà ninu wahala nla, gbogbo eniyan ni o si ri i pe ẹru ba ọba dé oju ikú. Bakan naa ni ẹru ba gbogbo eniyan.

Wo ipo aini iranwọ ti awọn ẹlẹṣẹ n wà nigba ti wọn ba kọ̀ lati yipada si Ọlọrun! Ọmọ Ọlọrun kò le bọ́ si iru ipo ti o ṣoro bayii nitori Ọlọrun wà ni tosi rẹ̀ lati ran an lọwọ. Ọlọrun wi pe: "Kepè mi li ọjọ ipọnju: emi o gbà ọ, iwọ o si ma yin mi logo" (Orin Dafidi 50:15). Ninu Jobu 5:19, 20, a ka a pe: "Yio gbà ọ ninu ipọnju mẹfa, ani ninu meje ibi kan ki yio ba ọ. Ninu iyan yio gbà ọ lọwọ ikú, ati ninu ogun yio gbà ọ lọwọ idà." Ogun dojukọ Bẹlṣassari, ṣugbọn àbá ati là kò si fun un. O ti sin ó si ti yin awọn ọlọrun wura ati ti fadaka, wọn kò si le ran an lọwọ. Ayé yii i ba ti kun fun okunkun ati ainireti to bi o ba ṣe pe kò si Ọlọrun ti a le yipada si!

**Daniẹl, Eniyan Ọlọrun**

Ayaba ranti pe awọn eniyan kan wà ni Babiloni ti wọn gba Ọlọrun gbọ́ ti wọn si n sin In. O sọ fun ọba nipa ọgbọ́n ti Ọlọrun fi fun Daniẹli ni akoko ijọba Nebukadnessari. O wi pe: "Li ọjọ baba rẹ, a ri

imọlẹ, ati oye, ati ọgbọn gẹgẹ bi ọgbọn Ọlọrun lara rẹ; … niwọnbi ẹmi titayọ ati imọ, ati oye itumọ alá, oye ati já alọ́, ati lati ma ṣe itumọ ọ̀rọ ti o diju, gbogbo wọnyi li a ri lara Daniẹli na" (Daniẹli 5:11, 12). Awọn ẹgbẹ́ ọmuti ti Bẹlṣassari ni kò le ran an lọwọ nigba ti o wà ninu wahala. Nigba gbogbo ni a maa n gbọ́ nipa awọn ti o ti padanu ohun gbogbo – ile wọn, ẹbi wọn, okiki wọn- nitori ọti mimu, ati pe ni akoko ipọnju wọn awọn wọnni ti wọn maa n sà wọn pe "ọmọ jaye-jaye ni," "onifaaji," "amereya" ki i sun mọ́ tosi lati ràn wọ́n lọwọ. Ni iru akoko bayii o yẹ ki wọn wá ẹni kan ti o ni "emi titayọ ati imọ," ati ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn rẹ ri.

Lẹsẹkẹsẹ ni a mú Daniẹli wá. Ni akoko iru apejẹ ti wọn n jẹ yii iru rẹ̀ ko yẹ ni ẹni ti a le pè sibẹ, ṣugbọn nigba ti wọn n fẹ ẹni ti yoo ṣe iranwọ o yọọda lati ṣe iranwọ. O n fẹ ṣe e fun ogo Ọlọrun, ki i ṣe nitori ẹbun ti ọba le fi fun un. O wi pe: "Jẹ ki ẹ̀bun rẹ gbe ọwọ rẹ, ki o si fi ẹsan rẹ fun ẹlomiran; ṣugbọn emi o ka iwe na fun ọba, emi o si fi itumọ rẹ̀ hàn fun u" (Daniẹli 5:17). Owo ati ọlá kò jamọ nnkan kan fun Daniẹli. Oun kò lepa lati de àye kan ninu eto ijọba naa. O n gbé igbesi-ayé ti o bu ọlá fun Ọlọrun ati eyi ti o wu U.

**Iwaasu Daniẹli**

Daniẹli kò kanju lati tẹ́ ọba ti ori rẹ̀ daru yii lọrùn. Akoko yii ni anfaani ṣi silẹ fun un lati ṣe iwaasu fun awọn ẹgbẹrun eniyan ti wọn jẹ́ ọlọrọ̀ ju lọ ni ilu naa, o si mu anfaani naa lo ni kikún. O rán ọba leti pe Ọlọrun ni O sọ baba rẹ̀ agba, Nebukadnessari, di ẹni nla; Oun ni O si fun un ni ọlá nla ati ogo ati ọlá. Nebukadnessari ni agbara to bẹẹ ti gbogbo eniyan lati orilẹ-ede gbogbo n wariri si aṣẹ rẹ̀. O ni agbára ikú ati iyè lori wọn – o le pa ẹnikẹni ti o ba fẹ. Ṣugbọn nigba ti Nebukadnessari di agberaga, Ọlọrun gba ogo agbara rẹ̀ kuro lọwọ rẹ̀. Daniẹli tun jẹ ki o di mimọ̀ fun Bẹlṣassari pe baba rẹ̀ agba ọba lọ gbé ninu igbẹ gẹgẹ bi ẹranko igbẹ titi o fi mọ̀ pe Ọlọrun ni alakoso gbogbo ayé. Nigba ti o si tun rẹ ara rẹ̀ silẹ, Ọlọrun tun gbe e ga.

Bẹlṣassari mọ̀ gbogbo eyi, ṣugbọn sibẹ o kọ̀ lati sin Ọlọrun, o si n gbé igbesi-ayé buburu dipo ki o sin Ọlọrun. Daniẹli mu iwaasu rẹ̀ wa si opin pẹlu awọn ọ̀rọ wọnyii: "Ọlọrun na, lọwọ ẹniti ẹmi rẹ wà, ati ti ẹniti gbogbo ọ̀na rẹ iṣe, on ni iwọ kò bu ọlá fun" (Daniẹli 5:23). Ohun ti o dara ni lati maa ranti pe Ọlọrun ni O n ṣakoso eemi ti a n mi. Eemi kan ṣoṣo ni o wà laaarin wa ati ayeraye, Ọlọrun si le ke e kuro nigbakigba ti O ba fẹ́. Bẹlṣassari yoo mọ̀ ki aṣaalẹ ọjọ oni to pari pe oun kò le fi kún ọjọ ayé oun jù bi Ọlọrun ba ti yọọda fun un lọ.

**A Sọ Idajọ**

Anfaani ikẹyin fun Bẹlṣassari lati ronupiwada ti rekọja. Nisisiyii Daniẹli sọ itumọ idajọ ti Ọlọrun ti kọwe rẹ̀ sara ogiri. Wọnyii ni awọn ọ̀rọ naa: "Ọlọrun ti ṣiro ijọba rẹ, o si pari rẹ̀. A ti wọ̀n ọ wò ninu ọ̀ṣuwọn, iwọ kò si to. A pin ijọba rẹ, a si fi fun awọn ara Mẹdia, ati awọn ara Persia". O hàn gbangba pe Bẹlṣassari kò jiyan rara nipa itumọ iwe naa ti a kọ. O fi ère ti o ti ṣeleri rẹ̀ fun Daniẹli, ninu eyi ti fifi Daniẹli ṣe olori ẹkẹta ninu ijọba rẹ̀ jẹ ọ̀kan.

Fun ọpọlọpọ ọdun ni ẹnu fi ya awọn eniyan nipa itumọ "olori ẹkẹta" yii. Bi o ba ṣe Bẹlṣassari ni ọba, ki ni ṣe ti ẹni ti o tẹle e ni aṣẹ pipa kò fi jẹ olori ekeji? Ni ọdun 1853, awọn ọjọgbọn nipa itan awọn ohun ti o ti wà ninu ayé ni igba laelae ṣe awari okuta igun-ile tẹmpili kan ti a ti kọ́ fun oriṣa kan tẹlẹ ri ni igba laelae, pẹlu akọlé awọn ọrọ wọnyii "ki emi, Nabonidasi, ọba Babiloni má ṣe dẹṣẹ si ọ. Ki ibẹru rẹ le maa gbé ninu ọkàn Bẹlṣassari, akọbi mi, ọmọkunrin mi ayanfẹ." Lati inu awọn ọ̀rọ akọlé miiran ni a ti mọ̀ pe Nabonidasi wa ni ibi isinmi ni ilu miiran ti ki i ṣe ilu Babiloni ni gbogbo igba naa, ati pe Bẹlṣassari wà gẹgẹ bi ajẹ́lẹ̀ baba rẹ̀ ọba. A tọka si Nebukadnessari gẹgẹ bi baba Bẹlṣassari, ṣugbọn baba rẹ̀ agba ni i ṣe, Nabonidasi gan an si ni baba Bẹlṣassari.

Bẹlṣassari gba pe ki Daniẹli jẹ olori ẹkẹta, ṣugbọn awọn ara Mẹdia ati awọn ara Persia gba ijọba ni alẹ ọjọ naa. A fi Daniẹli si ipo ninu ijọba wọn, awọn ọba titun naa si bu ọla fun un wọn si yẹ ẹ si.

**Babiloni**

Fun pupọ ninu ọdun marundinlaadọta ti Nebukadnessari fi jọba ni o fi kọ́ ilu Babiloni, ti o si ṣe e ni ilu ti o dara ju lọ ni igba laelae. Ọgba Babiloni ti a so rọ̀ soke jẹ ọ̀kan ninu awọn ohun iyanu meje ti o wà ni ayé. Ọ̀kan ninu awọn akọle Nebukadnessari ti awọn ọjọgbọn nipa itan awọn ohun ti o ti wà ninu

ayé ṣe awari rẹ̀ kà bayii: "Emi ti pari Imgur-Bel ati Nimitti-Bel, awọn ogiri nla ti Babiloni; ilu alagbara nì, ilu ti o ṣe apọnle agbara rẹ̀. Ni abawọle awọn ẹnu-ọna nla naa emi gbé awọn ere akọ-maluu ti a fi adalu bàba ati tanganran ṣe, ati ti awọn ejo buburu ti wọn duro ṣanṣan. Baba mi ṣe eyi ti ọba kan ko i ti ṣe ṣiwaju rẹ̀ ri. O fi afọnja ati amọ ṣiṣù ti a fi ina sun mọ ogiri meji ti a gbẹ́ kòto si idi rẹ̀ yi ilu naa ká, ati emi, pẹlu afọnja ati amọ ṣiṣù ti a fi ina sun, mọ ogiri kẹta ti a gbẹ́ kòtò si idi rẹ̀, mo si so o papọ mọ́ awọn ogiri meji ti a gbẹ́ kòtò si idi rẹ̀ eyi ti baba mi ti mọ. Mo fi ipilẹ rẹ̀ lelẹ lori ilẹ labẹ isalẹ omi; mo si mọ ogiri rẹ̀ bá oke dọgba. Emi fi amọ ṣiṣù ti a fi ina sun mọ ogiri ti a gbẹ́ kòtò si idi rẹ̀ yi ogiri ti o wà ni iha iwọ-oorun Babiloni ká."

Awọn oniwe itan ti igba laelae ṣe apejuwe awọn ogiri naa pe wọn ga ni ọọdúnrún (300) ẹsẹ bata, wọn nipọn to ọgọrin (80) ẹsẹ bata, ipilẹ wọn wọ inu ilẹ to ẹsẹ bata marundinlogoji (35) ki awọn ọta má ba le gbẹ́ abẹ ogiri wọnyii wọle. Oniwe kan sọ pe ipa meji ni a mọ awọn ogiri naa, apa kọọkan fẹ to ẹsẹ bata mẹrinlelogun ni ninipọn (24), alafo ti o fẹ to ẹsẹ bata mẹrindinlogoji (36), ni o wà laaarin ogiri mejeeji eyi ti a fi amọ kún, o dabi oju titi nibi ti ọpọ awọn kẹkẹ ẹlẹṣin le maa sare lọ ni ifẹgbẹ-kan-ẹgbẹ. Ọ̀kan ninu aṣẹku ogiri naa ti a hú jade lati ilẹ ni ẹgbẹ́ kan ti o dara ti o si lẹwa ti a fi amọ ti a fi ina sun ṣe lara eyi ti a ri awọn aworan nla ti awọn akọ-maluu ati ti awọn kiniun, aṣẹku ogiri naa ga to ọgọta (60) ẹsẹ bata.

Bẹlṣassari rò pe oun wà lai lewu niwọn-igba ti awọn ogiri wọnyii wà yi oun ká, ṣugbọn bi ase ọti mimu yii ti n lọ ni agbala ọba, Kirusi ati awọn ọmọ-ogun rẹ̀ n ṣaapọn lori didari odo ti o la aarin Babiloni kọja kuro loju ọna rẹ̀; lẹyin naa wọn bá ọna ti odo yii n gbà ṣan kọja tó wọ ilu. Ni alẹ ọjọ naa a pa Bẹlṣassari, gẹgẹ bi Daniẹli ti wi, a si mu ijọba Babiloni gẹgẹ bi alakoso aye wá si opin.

Bi o ti le wu ki awọn eniyan gbé ara wọn ga to lọjọ oni, Ọlọrun yoo rẹ̀ wọn silẹ nigba ti akoko ti Rẹ̀ ba to. "Awọn alaṣẹ ti o si wà, lati ọdọ Ọlọrun li a ti làna rẹ̀ wá" (Romu 13:1). "Nitori ti igbeleke kò ti ila-õrun wa, tabi ni iwọ-õrùn wá, tabi iwọ-õrùn, bẽni ki iṣe lati gusu wá. Ṣugbọn Ọlọrun li onidajọ; o sọ ọkan kalẹ, o gbé ẹlomiran leke" (Orin Dafidi 75:6, 7). Ọlọrun le jẹ ki nnkan maa lọ deedee fun awọn eniyan ibi fun igba diẹ lati mú ijiya wá ba awọn eniyan buburu, ṣugbọn nigba ti o ba ri i pe o to gẹ ẹ, O le ṣi ẹnikẹni lọwọ.

Ọpọlọpọ ijọba ni o ti dide ti wọn si ti ṣubu ninu itan agbaye. Ni ọjọ kan Jesu yoo tun pada wá, Oun yoo si sọ gbogbo ijọba kalẹ yoo si gbé ijọba ti ki yoo dopin laelae kalẹ. Oun ni yoo jẹ́ Alakoso yoo si jọba ni ododo, yoo si mú alaafia wá fun gbogbo ayé.

## AWỌN IBEERE

1 Ta ni Bẹlṣassari pè si ibi apejẹ nla ti o ṣe?

2 Ki ni wọn ṣe lati pe Ọlọrun nija?

3 Ki ni ohun ti o ṣẹlẹ laaarin apejẹ yii ti o dẹruba Bẹlṣassari?

4 Ki ni ayaba sọ nipa Daniẹli?

5 Ki ni ohun kin-in-ni ti Daniẹli ṣe nigba ti o de aafin ọba?

6 Bawo ni Daniẹli ṣe tumọ awọn ọ̀rọ iwe ti a kọ sara ogiri?

7 Iru ilu wo ni Babiloni? Ṣe apejuwe rẹ̀.

8 Ki ni Kirusi n ṣe nigba ti Bẹlṣassari n rò pe oun wa lai lewu niwọn igba ti oun wà ninu ilu oun?

9 Ijọba alakoso lori gbogbo agbaye wo ni o dide lẹyin ti Babiloni?

10 Ta ni ni gbogbo agbára lori awọn ọba ati awọn orilẹ-ede?